# ELETI OFE

'A-NJU-WON KO SE WI LEJO'

VOL XIV NO 943 LAGOS SATURDAY OCTOBER 17 — OCTOBER 23 1964 KOBO MEJI (2D

# Egbe Alatako Ilu Geesi Yege Idibo: Kurusof Olotu Rosia Fise Ijoba Sile

LONDON — Ni owuro ijeta ojo Alamisi ni gbogbo awon ara ilu Geesi ti beresi sare sihin sare sohun lati dibo lati yan Ijoba tuntun. Odun marun marun ni awon asoju ti yio ma se asoju fun won ninu ile igbimo



Gegebi irohin ti a ri gba ni ilu Oyinbo ni osan ann, awon omo egbe alatako ti oruko egbe won nje LEBO (LABOUR PARTY) ni idi bo won si nmoke. Ogbeni Harold Oilson Olori won ni o da on loju wipe egbe awon ni yio se Ijoba tunton fun awon ara ilu Geesi.



Aworan yi ni ti awon oselu ni ilu Oyinbo.

Odi odun ketala ni isiyi ti awon egbe Alatako na ti se alakoso Ijoba kan gbehin lehin ogun ajakaiye.

Ni oru ana na ni a gbo wipe alakoso ilu Rosia (Russia) Ogbeni Kurusof fi ise Olotu Ijoba won sile awon enia meji ni nwon yan si ipo re.

## Owo Olopa Te Baba To Gbe Arede [illegible]ejila

MESSINA (SICILY) – Ni ijarun ni awon olopa mu okunrin oko iyawo kan ninu sosi ti o ngbe arede owo ni iju Messina ni agbegbe Sicily ti awon si so sewon lori esun nini iyawo pupo, ati pe o di igba mokanla to ti oruka arede bo awon obinrin owo kiri, eleyi ni o bu okunrin na lowo, ti olobo ta awon Olopa nibi ise won.

Bi oko iyawo yi pelu iyawo re titun to se ikeji-la ti duro niwaju pepe si si lati gba ibukun fun igbeyawo na ni awon olopa ba mu, oruko oko iyawo na ni nwon npe ni Aldo Donati, eni odun mejilelogoji.

Gbara ti nwon ti mu u ni iyawo tituu na, eni odun merinlelogun ti o fe mu oru a arede mlron fu ba daku rangbondan, nse ni nwon fi moto ayokele gbe lo si ile alaisan fun itoju,

Oro okunrin na a ya awon ore ati ibatan iyawo alarede tuntun n lenu pupo, uwon ni awon ko tile fura si i wipe o ti gbe iyawo ri rara.

# ELETI – OFE

(A NJU WON KO SE WI LEJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFE" Lagos
P. O. Box 467, Phone 23370

VOL. XIV NO 943 SATURDAY Oct 17 — Oct. 23 1964.


ni Ọjọ Eti to kọja lori ẹsun jijale ọsan ganringan ninu eyiti nwọn fọ ile itaja obinrin to njẹ C.A. Ogunsanya ni Agbeni ni Ibadan ni Ọjọ Iṣẹgun to kọja.

Awọn ọlọpa sọfun adajọ pe nwọn ja ole na tipa-tipa, nwọn ji ẹgbẹrun le logorin pọnun o din mẹfa (£1,07ɟ) ati orisirisi siga ti iye owo wọn jẹ igba le okanleladọrin pọnun (£271 pẹlu awọn ọja miran ti iye wọn si jẹ pọnun marun din ladọrin, ati sile mẹtadinlogun (£65: 17/-) nwọn si uba ọrọ na lọ.

# Awon Oselu Fe Bere Ipade Egbe L'Eko

EKO—Gẹgẹbi n'an ti a gbọ, nwọn ni gbogbo ẹgbẹ awọn oṣelu nlaula kakiri iiu fẹ pade ui Eko ni ọjọ ejilelogun oṣu yi lati jiroro ati lati fi ohun ṣọkan lori awọn eto aṣepari fun idibo si ile igbimọ aṣofin ijọba apapọṣe to mbọ yi.

Ikede yi ni nwọn ṣe ni Eko ni alẹ ọjọ ai u to kọja lẹhin ipade kan ti gbogbo awọn ipinlẹ mẹrẹrin ṣe ni ile Olotu ijọba Apapọṣe, Alhaji Abubakare Tafawa Balewa ni Onikan fun n an bi wakati mel, ninu eyiti Olotu ijọba apapọṣe ṣe alaga ipade na.

Ninu ikede alabẹ ṣekele kan to jade kete lẹhin ipade na, nwọn ni ọrọ to jẹ mọ idibo to mbọ yi wa ninu ajọṣọ ipade na, ati fifi ohun ṣọkan lori yiyan awọn aṣoju lati inu awọn ẹgbẹ oṣelu pataki-pataki ni ọjọ kejilelogun oṣu yi.

Awọn to wa sibi ipade na ni awọn Olotu ipinlẹ mẹrẹrin bi Ọlọla Alhaji Ahmadu Bello (lati ipinlẹ Ariwa) Dokita M.I. Okpara (lati Ila Orun) Oloye S.L. Akintọla (lati Iwọ Orun) ati Oloye Dennis Osadebay (lati Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun.

Aye ti o ni aluku wa ninu ẹgbẹ rẹ niwọnyi- Alhaji Ahmadu Bello, Sardauna ti Sokoto ni o jẹ asiwaju ẹgbẹ Ajumọṣe (NNA) ninu eyiti ẹgbẹ olomi ẹgbẹ Dẹmọ, MDF ati ti NDC wa, bẹ gẹgẹ si ni ti Dokita M.I. Okpara to jẹ Aṣiwaju ẹgbẹ Alakuko ti nwọn wa parapọ pẹlu ẹgbẹ Olọpẹ ati NPF ẹka ẹgbẹ kan ni ipinlẹ Ariwa.

Oloye Akintọla ni o jẹ aṣiwaju ẹgbẹ Dẹmọ, bi Oloye Osadebey si ti jẹ igba keji babasalẹ fun ẹgbẹ Alakuko. Olotu ipinlẹ iha Ariwa ni o kọkọ de si Eko ni ọjọ Aiku fun ipade yi, bakanna si ni ti awọn Olotu ipinlẹ Ila Orun ati ti agbedemeji Iwọ Orun ti nwọn jọ ba ọkọ ofurufu de si Eko ni ọjọ kanna.

Ọna ilẹ ni Oloye Akintọla gba de si Eko lati Ibadan, ṣugbọn dide rẹ ko han si enikẹni. Gbogbo wọn ti pada si ilu wọn ni alẹ ọjọ kanna.

# Olopa Mu Awon Danadana Meji Ni Ibadan

IBADAN — Awọn ọkunrin meji ti awọn nṣe danadana ti oruko wọn njẹ Ade Ọmọ Oloye tabi "Bi T'Eko" ati Ademola Odvino ni a gbọ pe awọn ọlọpa mu lọ si kootu adajọ awọn ọlọpa ni Ibadan

# Omo Odo Kan Fi Tipatipa B'omo Oga Re Lopa

EKO— "Ori iduro ni mo wa nigbati mo di ologbo pada fun ọdaran na o ju ologbo na nami pada o tu mi ni ṣokoto awọtẹlẹ o yọ kini kan jade lab rẹ o si fi kini buruku kan bọ mi labẹ."

Eyi ni alaye ti adajọ kotu kekere kan ni Yaba gbọ ni ọjọ Iṣẹgun to kọja nigbati awọn ọlọpa nṣe ẹjọ nipa ẹjọ biba ọmọge Oyinbo kan to pọ lajijẹ ifẹ inu rẹ.

Gẹgẹbi nkan ti awọn ọlọpa wi nwọn ni ọkunrin kan to nṣe ọmọ-ọdọ labẹ Oyinbo kan to njẹ Joel Ndukwe ba ọmọ ọga rẹ to njẹ Barbara Hinmarsh lo pọ lajijẹ ifẹ inu ọmọge Oyinbo na ni ọjọ kejidinlọgbọn oṣu kerin ọdun yi ni nkan bi agogo mẹfa kọja iṣẹju mẹd gun ni ir ẹ ni opopo o Alhaji Kanike ni Ikoyi l'Eko.

Ngbati Barbara njẹri lori ọrọ na o ni o di oṣu mẹta ti on ati awọn obi on ti ngbe Ikoyi on ko si ni ale tabi ọrẹ kan kan rara ati pe on asi ma digbẹrẹ ṣere lọ si ile ọmọ-ọdọ na ninu yara to ngbe on asi ma fi ologbo ọdaran na ṣere lajijẹki o han si iya on nitoripe iya on ti ki lọ wipe on ko gbọdọ ba awọn ara ilẹ Naijira ṣere rara tabi ki on ti'ẹ dara pọ mọ wọn.

O sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe ni ọjọ na gan on bi ọdaran na lere pe ki o fun on ni ologbo rẹ lati fi ṣe re o si ṣe bẹ bẹni on ba gbe ologbo na lọ, ṣugbọn nitoripe awọn obi on ko ni epoti ti on le fi ologbo na s, on ba da pada, a o-ko ti on s da ologbo na pada ni ọdaran ju lu on pada.

Barbara ni ngbana ni o ba ti on sinu yara re o tun tu ṣokoto awọtẹlẹ nidi on o fa kini gigun kan yọ jade labẹ re o si ki bọ on nidi Dokita Ṣọ'n Saraki to nṣiṣẹ ni ile alaisan to wa ni Ikoyi fi iwe ẹri kan ha adajọ gẹgẹbi ẹniti o ṣetoju Barbara ati iwadi nkan to ṣẹlẹ si ọmọge na larin ọjọ kẹtadinlogbọn si ikokandinlogbọn oṣu kẹrin ọdun yi

Dọkita na tun sọ pe on ni o ṣe itọju Barbara ti on si fi odidi ọjọ meji gba ko fun ni abẹrẹ nitoripe gẹgẹbi iwadi ti on ṣe on ri wipe nise ni abẹ ọmọge na nṣẹjẹ pẹlu aye kan to si s lẹ lati oju abẹ rẹ. Ọmọbinrin agbẹjọro kan ti oruko rẹ njẹ Ebube ni o ngbe ẹnu sọ fun ọdaran na ṣugbọn atongbọ ẹjọ na di ọjọ kẹ adinlogun oṣu yi

# Ijoba Ariwa Padanu Iwe Eto Oruko Idibo

KADUNA — A gbọ wipe ọpọlọpọ aṣiṣe ati alọjufọdi ni awọn ri ninu iwe eto iforukọsilẹ fun idibo ti nṣe tì ijọba ilẹ Ariwa ti Naijiria, eyiti nwọn kọkọ tẹjade fun apere nwọn si ṣapejuwe iru aṣiṣe bayi gẹgẹbi ohun to burujù lọ papa nipa awọn ilu Borno, Niger, Ṣokoto, Adamawa ati awọn ilu agbegbe Zaria.

Gẹgẹbi ikede kan ti nwọn tẹ jade lati ile iṣẹ Olotu irohin ijọba ilẹ Ariwa ni Kaduna ni Ọjọ Iṣẹgun to kọja nwọn ni ... esi alakoso lori eto idibo fun ijọba Apapọ lati fi ẹda awọn apa iwe na to ti sọna ranṣẹ si wọn ... le ṣe atunṣe ... ran.

Ninu ikede na nwọn ni kete ti awọn iwe wọnyi ba ti tẹ wọn lọwọ nwọn yo fi awọn apa kan rẹ to jẹ ... si awọn ilu ti awọn gbe iforukọsilẹ ti o faraKọ ... si ibi ... duro.

Lọwọlọwọ yi gbọgbọ ... ilu ... ni ipinlẹ Ariwa ni nwọn ti ... iwe oruko wọnyi ... kakiri ... awọn ... si ... ka iwe ... si ri oruko wọn nibẹ ni nwọn ti bẹrẹ ṣe ... ẹ ... lati bi ọjọ meji wa.

Ninu iwe ikede ti nwọn tẹ jade nwọn ni ohun ti o mu ki awọn ... iwe oruko wọnyi kakiri ... lati le jẹki eto iforukọsilẹ na le gun rege ki o si fi oruko awọn ti nwọn ba ni ẹtọ lati dibo ... nani wọn yo si lo ni akoko idibo to n bọ yi.

# Loya Oyinbo Kan Safojudi Si Kotu

DAR-ES-SALAAM — Loya Oyinbo alawọ funfun kan ti oruko rẹ nje Lockheart Smith ẹni ọdun mejilelọgọta ni adajọ kotu kan ni ki o lo fi ponun mẹdogun ati ṣile mẹdogun tanran fun ... ikotu fi.

Ọgbẹni Lockheart Smith ti o ti jẹ oṣiṣẹ ijọba ilu Gẹ si tẹlẹri ṣ... adajọ na pe on ko jẹbi ẹsun mẹta ti nwọn fi kan on ati pe ni kẹhin o ni on yio pe ẹjọ kotẹmilọrun.

Awọn ọlọpa ni loya na huwa alailọwọ si adajọ Naijiria kan ti oruko rẹ njẹ Emmanuel obi Echetabu o si gbidanwo lati binu jade kuro ... kotu nibiti nwọn gbe nṣe ẹjọ kan lọwọ pẹlu aibikita lati fi han pe on ko nṣu ... dun lati ma ba ẹjọ na lọ o wa sọfun adajọ na pe

"Ki nwọn to bi ọ ni mo ti nṣe loya mọ si ni imọ ... ninu iṣ ... kotu ju iwọ lọ"

Ọgbẹni Lockheart-Smith ti nwọn bi ni ilu Hongkong ti fi igba kan ... ṣe ... alaṣẹ eto ... fun ijọba ilẹri ki o to wa jẹ adajọ agba ni ilu Nyasaland.

On kanna ti tun jẹ adajọ agba ri fun kotu Tanganyika ti ile Gibralter N... gbati adajọ nṣe ... rẹ, aṣẹlẹ adajọ ọgbẹni A. O. Agbebi ọmọ ilu ... gan yin

# Olotu Ijoba Geesi Ko Ni Dibo Nilu Oyinbo

LONDON — Nwọn sọ nilu Oyinbo latipe ... pe Olotu ijọba ilẹ Gẹẹsi, ọlọla Alex Douglas Home ko ni ẹto to lati dibo sinu ile igbimọ aṣofin ijọba Gẹẹsi ninu ibo didi ti nwọn fẹ ti nwọn fẹ di kakiri ilu ilu Oyinbo ... oṣu yi.

A Gẹgẹbi ... a gbọ nwọn ... Ọlọ... Alex fi ... a ... sile ... pe ... awọn aṣofi ... Ọla (House of Lord) ... ilu Oyinbo ... o to di Olotu ijọba Gẹẹsi, ni ọdun to o kọja ... eyi o wa gbagbe lati foruko rẹ silẹ ninu iwe idibo ti awọn aṣofin ... ogbogbo (House of Commons) ni ilu rẹ ni Berwick ati East Lotian.

Ko si aniani awọn ọmọ ẹgbẹ oṣelu Ọlọla Alex ... awọn yio dibo fun ... lati le pada si aye rẹ gẹgẹbi Olotu Ijọba awọn.

Awọn Oloye ilu Gẹsi ni awọn ṣe akiyesi wipe bi nkan ti nlọ yi awọn ẹgbẹ oṣelu ti nwọn ... Conservative Party ... yio bori idibo ... su bọn ... awọn ọmọ ẹgbẹ Labour Labour Party ... sokoto wọn ... lati jagun molu lori ... dibo na.

Ju gbogbo rẹ lọ a gbọ wipe Ọlọla Douglas Home na ti fi oru ... ọsilẹ ni ijẹrin wipe ki awọn ara agbegbo on dibo fun on

# Bisobu Agba Wasu F'Alake

ABẸOKUTA — Ni ọjọ Aiku to kọja nigbati Alake Abẹokuta, Ọba Adesina Gbadebo keji nṣe idupẹ ni Ṣọ... si fun ajọyọ ọjọ bi fun pipe ẹni ọdun mẹrindinlọgọta ati ọdun kinni lori oye, ni ilẹ Ẹgba ni Abẹokuta awọn gba... niwaju lati sa ipa rẹ lọnakọna ki iyi ati ogo ti awọn aṣiwaju rẹ ti ni nikawọ ri pada bọ si ilẹ Ẹgba.

Alufa ẹni ọwọ S.I Kale to gba ... niyanju tun sọ fun ... ki o lo akoko rẹ daradara fun idagba ati ilọsiwaju ile Ẹgba nitoripe nipa ṣiṣe bayi papa pẹlu awọn ... rẹ on yio le ni oye ati imọ lori iṣoro ati nkan ti nwọn fe ati ... ti le wa ọna lati ṣe atunṣe awọn iṣoro bawọ yi.

Bisọbu ... S.I Kale ... ọba na ... daju pe Abẹokuta ni ... ipilẹṣe ẹsin igbagbọ ... si ti pe ... maa ni ... nkan ti mba ṣe ... aiye lọ, ki o si fi ... rere han bi ... a ọn ọba to ti jẹ ṣ... ju rẹ papa nigba aiye ijọba awọn Oyinbo.

Lẹhin ipari isin, Bisọbu na ki Ọba Gbadebo ku oriire ọjọ ibi o si ni yio ṣe opo ọjọ ibi ati iṣẹ rere si Ọlọrun ati ... nwọn wa si ibi isin idupẹ ajọyọ ọjọ ibi rẹ lati Eko ati apa Iwọ Orun Naijiria.

Awọn to wa sibẹ ni awọn bi Minista, fun ijọba ati alakoso ẹsin ọmọ ẹgbẹ ile igbimọ aṣofin awọn ọba ati awọn ijo ... a.

Losan ọjọ na Alufa Dokita J O E. Ṣorẹmekun ti nṣe baba ẹgbẹ ijo ṣọṣi Methodisti ni Naijiria gba Alake niyanju lati di Ọlọrun mu gidigidi lati ọdọ Euiti on yio ri anu gba lati maa fi ṣe iṣẹ rẹ.

# Egbe Demo Ni Oro Dokita Okpara Ko Waiye

EKO — Ọpọ ọrọ ni nwọn fi sọko si Dokita Okpara ti nṣe aṣiwaju ẹgbẹ Alakukọ lori ọrọ kan to sọ jade sinu iwe irohin ni ọjọ Aje to kọja, ninu eyiti nwọn ni o sọpe awọn aṣiwaju ẹgbẹ Dẹmọ nnaga lati di ọmọ ẹgbẹ U P G A to jẹ ajumọṣẹ ẹgbẹ Alakukọ ati ti Ọlọpẹ.

Ninu irohin kan ti ẹgbẹ Dẹmọ ṣe jade ni Ọjọ Iṣẹgun: nwọn ni ko si otito kanṣoṣo ninu ọrọ Dokita Okpara rara, nitoripe ero imulemufo lasan ni, eyiti ko tilẹ yẹ enia toḳwa nipo giga gẹgẹbi aṣiwaju ẹgbẹ oṣelu kan lati ma sọ jade.

Ọrọ irohin na tun ni abuku ti ko lẹgbẹ ni fun Dokita Okpara lati mẹnu kan ọ̀rọ̀ ... ati ẹni ọwọ to jẹ aṣiwaju ẹgbẹ awọn, Oloye S.L. Akintọla ninu iru ọrọ ailotitọ yi," ati pe iru ikede irọ bayi ki iṣe nkan ti enia le pe ni nkan ere.

Nwọn ni ki iṣe inu didun tabi ifẹ ẹgbẹ Dẹmọ pe ki aṣiwaju wọn kan di ọmọ ẹgbẹ UPGA to dabi ọkọ to nri sinu omi, nipa bayi nwọn tun sọ pe kini ẹgbẹ UPGA jẹ bikoṣe oku ẹgbẹ Alakukọ nitoripe ọrọ rirun ati aiṣododo ti ajumọṣe awọn ẹgbẹ mejeji wọnyi nsọ jade to lati le enia lọ nilu.

Ninu iṣẹ apeuwe tabi alaye bi ẹgbẹ N.N.A ṣe wa ni pelu UPGA, ẹgbẹ Dẹmọ ni "Fun ẹni ọ̀kan ninu awọn aṣiwaju awọn lati di ọmọ ẹgbẹ UPGA tabi ọkan ninu ẹ̀ka ẹgbẹ na, o dabi igbati enia ti inu imọlẹ bọ si o un-un, ti enia fi ilọsiwaju ropo ifasẹhin ati alafia ropo rudurudu, nitoripe gbogbo iya, iṣoriri ati aidọgba awọn ipese anfani ti ijọba apapọṣe fẹ fi da enia lọla ti ko si to wọn lọwọ, ati eyiti nwọn njiya fun titi di oni jẹ iṣẹ ọwọ ẹgbẹ UPGA."

Nwọn ni ni agbara Ọlọrun ẹgbẹ NNA ati ifẹ awọn enia, yio bori awọn ọta wọn ninu idibo ijọba apapọ to nbọ yi, ati pe ọkọ ti awọn wa ninu rẹ yi jẹ ọkọ iṣẹgun.

# Fani Kayode Ni Ki Yoruba Ma Gba Were M'Esin

ỌWỌ — L'ọsẹ to kọja, a gbọ wipe Igba Keji Olotu ipinlẹ Iwọ Orun, Oloye Fani Kayọde ati Minista fun akoso ijọba ibilẹ sọ fun awọn ara ilu Ọwọ lati gbagbe ohun to ti kọja, bi gbigba were mẹsin nipa fifarumọ ọrọ ẹtan ti awọn ẹgbẹ oṣelu miran nsọ fun wọn ati pe ki nwọn tẹpa mọṣẹ lati wa ni irẹpọ pelu awọn ara ilu miran ki Yoruba, gẹgẹbi orilẹ-ede kan le gberi ninu ijọba apapọṣe ti Naijiria.

Ọrọ yi ni Fani-Kayode sọ nigbati o nba awọn ara ilu Ọwọ sọrọ ninuojo kan to rọ lojọ na, ninu gbọngan nla to wa nibẹ. o si tun sọ fun wọn pe Yoruba ti ri imọ̀ẹ nisisiyi, o wa ku si wọn lọwọ lati lo anfani yi lona to ọ, ati pe ki nwọn wa ni irẹpọ, nitori bi ede aiyede kan ba ṣẹlẹ larin wọn, yio ni anfani lati pari rẹ fun anfani ti ara wọn ati ti ọmọ wọn pelu.

Oloye Fani Kayode ni tiṣẹ eju ọna reluwe titi de Ọwọ, dida ọda si awọn titi ulaala ... ataki kiọ ibudo ọkọ ofurufu ati dido ile iṣẹ ... ni ijọba apapọ yio ṣe, nitorina ki nwọn dibo wọn fun ẹgbẹ Dẹmọ ki nwọn ba le ni idera ati igbadun nla. Ki o to fi Ọwọ silẹ, o kesi Oba Ọwọ, Ọlọla Ọlateru Ọlagbegi keji lati ki i.


E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

ELETI—OFE

ti o kun fun irohin aladun losose.


# Eleti-Ofe Daraba

E ka oro Ijoba Ariwa padanu loju ewe keta

# BBC To Report "Men In Power"

A special post election report, called "The Men in Power" about the personalities of the men who have been elected in Britain's General Election, will be broadcast in BBC's programme for West Africa on Wednesday, October 21, at 11.30 GMT on 21.61,17, 81 and 15,235 megacycles in the 13,16 and 19 metre bands.

During the recent election campaign, the BBC African Service has recorded scenes at election meetings throughout the country that give a dramatic impression of the British parliamentry election system at work. The scene at the anuouncement of the voting in the Prime Minister's constituency will be one of the many recorded highlights. Political commetators from Britains leading newspapers will also be heard in the programme, giving an overal impression of the enormous press, radio and Television coverage of the 1964 election compaign.

ZAMBIA'S INDEPENDENCE

On October 24 Northern Rhodesia or "Zambia" as it will be known becomes an independent sovereing state To mark the birth of this new nation the BBC African Service is broadcasting THE 36TH STATE, a programme that commemorates Zambia as the 36th country in Africa to become indepent.

THE 36TH STATE, which is broadcast on Friday, October 23, at 1145 GMT, describes Zambia and its people and how independence has been achieved the voice of Dr. Kenneth Kaunda, the Prime Minister elect, will be heard in the programme

Zambia's independence is also celebrated by the BBC African Service with a special variety show for Africans in London at the SIMBA CLUB The show will be attended by some 400 Zambia and other African well-wishers, and highlights from it will be brodcast on Sunday, Oct. 18, at 11. 18 GMT on 21 61, 17 81 and 15. 2.35 megacyles in the 13,16 and 19 metre bands.

The SIMBA CLUB artist include top singing star from Southern Rodesia, Dorothy Masuka; from Britain's beat-wave city, Liverpool, the Ghanaian-born Chants from South Africa the popular Woodpeckers; and from Mombas East Africa's pop singer Sal Davis Zambians in London will complete the entertainment with Songs from their homeland and the packed audience is expected to stay on talking and dancing until late in the evening

# Nigeria's first landscape Architect

LONDON, — A Nigerian graduate at the University of Newcastle on Tyne in north-east England has become his country's first qualified landscape architect.

Mr Emmanuel Akah, 36, an employee of the Ministry of Agriculture (Forestry Division) in Enugu, received his Diploma in Landscape Design following a year's post-graduate work at Newcastle, under Nigeria/U.K techinical assistance arrangement

In an interview with our L.P.S. correspondent, Mr. Akah said he was "thrilled" at being the first Nigerian to qualify in this field.

"Landscape designers," he said "have an important role to play in the future development of Nigeria. With the present rate of industrial, housing and population growth, it is essential that the best possible use is made of the country's natural attractions.

Before studing landscape desing, Mr Akah spent two years studing forestry at Oxford University. He and his wife and three children will arrive in Lagos by sea on October 22.

# Work Begins On 500-Mile Oil Pipe

LONDON — Work began recently on the 500-mile pipeline designed to carry over ten million tons of crude oil a year from the Shara wells to the Algerian Mediterranean port of Arzew,

Mr. Edward du Cann, Minister of State at the British Board of Trade, said at the inauguration ceremony that the £25,000 000 contract was the biggest ever awarded to the British firm in North Africa.

Last Sunday, a plant was opened at Arzew for liquefying natural methane gas for shipment to Britain.

Shipments of gas made under a 15-year contract with the British Gas council would ultimately be worth £6. Million a year, Mr. du Cann said.

Read And Advertise In ELETI—OFE

# Oko Iyawo Pale Le Iyawo Re Lori

ABBA— Lyse to'kọjɪ iyawo kan ti orukọ rẹ njẹ Ọmọjagbara Alerishe sọfun adajọ kotu to wa ni ipinlẹ ilu Kabba wipe John Alershe to jẹ ọkọ on fun on ni majele jẹ ti o mu ki on maa şşe nka oşu ti laidawo duro.

Ọrọ yi ni Ọmọjagbara sọ nigbati o njẹri tako ọkọ rẹ ti awọn ọlọpa mu fun ẹsu farawe o si tun şe alaye pe ọkọ on fi majele na ranşẹ si on ni o.u kọ baba to bi on ti o nje Onope Ehibiebaiye nigbati on ngbe Eko lọdọ awọn enia on nitori ede aiyede kan to şẹlẹ larin awọn mejeji.

Obinrin na ni ọdaran ọkọ on tun fi iwe kan ranşẹ pẹlu majele na o wa iọọ bi ẹni wipe baba on lo fi wọn ranşẹ si on nigbati on si ri nkan wọnyi gba on ko fura si majele na bi o ti jẹpe ọdọ baba on ni nwọn ti mu wa bẹni on ba iẹẹ

Obinrin na ni ni alẹ ọjọ ti on jẹ majele na ko si igbadun fun on rara lati ọjọ na wa ni on ti nri nkan oşu on ti ko si ti fi ọjọ kan duro rara ati pe nigbati on pada lọ si Kabba on ba ro ọjọ na fun baba on nkẹhin aşe ọkọ to fẹ on ni elẹşu lehin on.

Nigbati ọrọ kan baba iyawo ọgbẹni Onope Ehibiebaiye o ni ki işe on ni o kọ iwe si ọmọ on bẹni majele kankan ko si ti ọwọ on koja şọdọ ọmọ on ni Eko.

Nikehin John Alerishe gba ẹbi rẹ o si bẹ adajọ ki o şanu fun on nigbana ni adajọ ni ki o lọ fi pọn un mẹwa ati silẹ mẹwa tanran tabi ki o lọ sẹwọn oşu kan ti ko ba riowo san ki o si tun san pọnun merin ati şile meje fun iyawo rẹ fun owo ituninu.

Balẹ kotu ọgbẹni A. E. Olowosuia wa gba ọkọ iyawo ọna nimọran ki o lọ wa egbogi miran şe ti yio pa majele na patapata eyiti o ti şe abuku buruku lara obinrin na.

## Jaguda Bo Saiye Ni Ilu Oyinbo

LONDON — Lọjọ kejila oşu yi, ọrọ ikede igbaniyanşẹ kan jade ninu iwe irohin ojumọ ni Londọni bayi pe –

"A nfẹ ogbologbo jaguda to ti jawọ kuro ninu işẹ jaguda fun işẹ patiki kan gẹgẹbi Olugbani nimoran ninu oni işẹ jaguda fun şişe ere sinima alailupayida"

Ikede na tu fi yeni wipe iru işẹ ti nwọn kede rẹ yi jẹ eyiti o ba ofi lọ ati wipe gbogbo esi ti nwọn ba ri gba lati ọdọ awọn jaguda ni yio wa aşiri, awọn ko ni jẹki awọn ara ilu mọ oruko awọn jaguda na.

## Northern Nigeria Government Plans Irrigation System

LAGOS — The Government of Nigeria's huge arid Northern Region plans to construct a large-scale irrigation system through Northern Nigeria, Premier Alhaji Ahmadu Bello, the Sardauna of Sokoto announced. A new Minister of Water Resources will be created which will construct small dams in every district The Daily Times called the plan "bold and revolutionary" and congratulated the Northern Government on "its foresight and determination to improve the lot of the farmers."






# Ka oro Olotu Ijoba Geesi

loju ewe kinni

# E ka oro baba alarede mejila

loju ewe karun

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O 467, Lagos.